Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

**Akiyesi Pataki**

A nfe aṣo'ju lati awọn ilu nwọnyi lati ma ta Iwe Irohin Eleti-Ọfe ati lati ma ṣe aṣoju wa nibi gbogbo ti nkan ariwo ba ṣẹlẹ: bi Ife Ijebu Ode Ilesha Osi Oke-Ode Ajasse-Ipo Omu Aran Ilorin Offa Ede Ondo Owo ati Akure.

OLOTU

VOL. X No. 591. LAGOS, SATURDAY, SEPTEMBER 27—OCTOBER 3, 1958 KỌBỌ MEJI (2d).

# NWON PA NI TABI O FI OWO ARA RE PARARE ?

EKO. Ibere kanna ti awọn ọlọpa Eko ati ti Portharcour iti le dahun rẹ ni eyi. "nwọn pa ni tabi ọwọ ararẹ l'ofi pararẹ" ? Ibere yi jade lori obinrin abilekọ meji ọkan nilu Eko, ekeji nilu Portharcourt.

Ti ilu Eko ni iku obinrin abilekọ kan ti nwọn ba oku rẹ ninu yara ọkọ rẹ ni Odi-Olowo, eyi ni awọn ọlọpa pe ni iku aimọdi. Awọn Ọlọpa ti pe ọkọ rẹ, nwọn si ti gbọ t'ẹnu rẹ.

Nilu Portharcourt, obinrin abilekọ kan ni a gbọ pe nwọn ba oku rẹ ni iyara ọkọ rẹ bakanna ni adugbo Diobu. Awọn ọlọpa koiti ri ọkọ rẹ bi lere ọrọ. Awọn alabagbele pọ obinrin na sọ wipe lati nkan bi ọjọ mẹta ni nwọn ti ti ilẹkun yara na ki oorun buruku to bẹrẹ si jade lati yara na.

Nwọn ti gbe oku mejeji lọ fun ayẹwo Dokita.

## Ayajo Ti Ojo Ibi Anobi Muhamad

Friday ọjọ 25th oṣu September 1958 ni ọjọ ti gbogbo awọn Musulumi agbaiye ṣe iranti ọjọ ibi Anọbi Muhamad. Lọjọ na ni gbogbo awọn enia ni gbogbo ilẹ Nigeria gba isimi kuro lẹnu iṣẹ Musulumi ati Kiriyo lo jijọ kara kun arisiki ọjọ na, awọn mejeji si mba ara wọn ni ajumọsepọ.

Sala lahu alahin wasalam.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Nathaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS, HAMBURG.

## Ha! Eja Nla Lo L'omi



Aworan ti a nwo ninu iwe wa yi niti Ologbe Alhaji Adegoke Adelabu, Aṣiwaju ijọ Alatako ninu ile igbimọ Aṣofin Iwọ-orun, nilu Ibadan, ẹniti o ṣe agbako iku ojiji rẹ l'ọna Ode-Rẹmọ nitosi ilu Shagamu ninu oṣu March tokọja.

Gbogbo awọn Oṣelu enia wa ti nwọn lọ silu Oyinbo fun eto ominira ilẹ Nigeria ni yio ranti Ologbe na lawujọ wọn, gẹgẹbi o ti jẹ pe ọkan-ṣoṣo ajanaku to nmi igbo kijikiji ni iṣe.

Adelabu Ọrun rere.

## Adamodi Dokita Fara Korin

ENUGU Ọkunrin kan ti ko kọ iṣẹ Dokita ri, ti a ko si gbọ wipe o ṣiṣẹ labẹ Dokita kan ri, ni awọn ọlọpa ramu fun ẹsun wipe, o gun awọn enia ni abẹrẹ laigba iwe aṣẹ tabi lajẹ Oniṣegun.

Ọdaran na njẹ Musa Abudulahi, o ni awọn egbogi oyinbo ti o lewu lọwọ, o ni abẹrẹ ti awọn Dokita fi ngun enia ni apa, o si tun ni awọn egbogi oriṣiriṣi ti a fi ngun enia ni abẹrẹ lọwọ.

Ọdaran na ko le sọ bi nwọn ti ṣe, de ọwọ rẹ, ṣugbọn awọn Ọlọpa lero wipe ko ni iwe aṣẹ lati ni irufẹ egbogi bẹ lọwọ.

Ọwọ tẹ ẹ nilu kan ti nwọn npe ni Apugo ni agbegbe ilẹ Enugu nibiti o gbe ngun wọn ni abẹrẹ. Enia marun ti o ti gun ni abẹrẹ na ni wọnyi:- Ezekiel Edeani, Nwachi Ogbu, Okorie Nuodo Okonkwo Onyeabo ati Nnam Nwoma.

Adajọ ṣa konko Pọun marundinlọgọjọ mọ lara tabi ki o lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹdogun.

## [illegible] Morning Star Ibadan Branch Se Ipade.

[illegible]



## Awon Omo Oyinbo Fi Ara Won Jin Fun Ise Nile Enia Dudu

LONDON. Awọn ọmọ Gẹsi lo fi ara wọn jiu lati kọ awọn enia dudu lẹkọ ni ọfẹ laigba owo, bi awon enia dunu ba le sanwo ọkọ wọn owo onjẹ ati owo ilẹ, o tan awon yio wa silẹ wọn lati ko wọn ni Ohunkohun ti nwọn ba fe.

Awọn meji yio duro nilẹ Ghana, meji yio wa ile Nigeria. Mẹrin ni awọn ti o kọkọ gba lati fi ara wọn jin fun iṣẹ ilọsiwaju ẹkọ ni agbegbe Iwọ - orun ilẹ Afrika, ninu awọn ẹgbẹ kan ti nwọn da silẹ ti a npe ni "Voluntary Service Overseas 1958.

Ogun ni awọn ọmọ ilewe ti nwọn gba lati fi ara wọn jin ti olukọ agba yan fun iṣẹ yi, awọn enia mẹrin ti o nlọ si Afrika na jẹ ọmọ ọdun mejidilogun. Awọn meji ti o mbọ nilẹ Nigeria yio lọ si Man o'w.r Eay nilu Kamaru n ibẹ ni nwọn o ti ma kọ ni lẹkọ.

## Kini Michael Fe Fi Rifofa Se

ENUGU. Okunrin kan ti o nje Michael Ogwa ni awon olopa ramu fun esun wipe, nwon ri ibon Rifofa (Revolver) ati ota metadilogoje lowo re. Kini ohun ti o fe fi se? Ko si eniti o le so.

Awon olopa so wipe, nwon ba orisirisi aworan lowo re, ti o je ti Eastern Nigeria Information Service A gbo wipe larin oja ni awon Olopa ti ki okunrin na mole nibiti o gbe yo ibon ilewo yi dani.

Adajo ni ki o lo san atota poun tabi ewon osu merin.


Igbadun wa ninu

Oti Heineken's

To Oti Heineken wo fun ara rẹ! Iwọ yio fẹ adun rẹ – yio Si da o ...
igbadun Nitorina ...
lati mu oti Heineken
Ni alẹyi ko oba le ni
agbara ni aro ...
pẹlu ...




Orun ... pelu agbara lo sọ

Oti Heineken's

di Olo... laiye


## Jamba Inu Osu August 1958.

IBADAN Awọn enia t i ẹmi wọn ṣegbe ninu awọn jamba to ṣelẹ ninu oṣu August 1958 ni agbegbe Iwọ-Orun jẹ mẹtale-ladọrun

Bi awọn ọlọpa ti ṣe iṣiro awọn ti jamba ṣelẹ si na niwọnyi :- Ninu awọn jamba nwọnyi, enia mẹsan lo ku bamu-bamu, enia mejilelọgbọn lo fi ara ṣeṣe.

Mọto wiwa buruku-buruku ṣe iku pa ogoji enia, aiṣe iṣẹ daradara mọto ṣe iku pa enia mejidilogun.

Lọwọ iku gbigbona ati iku ojiji, Oluwa r e r e gba wa.

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRA

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - ỌFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL, NO. X. 591. LAGOS, SATURDAY SEPT. 27 - Oct. 3 1958.


## Aki Ifi Ina S'ori Orule Sun

Cẹgẹbi owe Yoruba mọni-mọni ti o sọ wipe "Aki ifi ina s'ori orule sun" ni ọrọ ti awa Eleti - Ọfẹ le sọ le ori ọrọ ti a gbọ wipe Dokita Azikiwe ti iṣe Olotu ijọba ilẹ Ibo ni Ila - Orun ati Akonijẹ ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C.) sọ nilu Oyinbo nigbati awọn Oniwe irohin ni ipade pẹlu rẹ, wipe gbogbo koko - ọrọ ti ko ba ṣe yanju ki awọn fi silẹ tabi ki a pati s'ẹgbẹ kan, bi o ba di ẹhin oṣu mejila ti a ti gba ominira, ki a wa yan igbimọ ti yio joko jiroro ṣe eto iyanju awọn koko - ọrọ bẹ.

Loju tiwa, imọran ti ko mọyan lori ni eyi jẹ, nitoripe eto ifaiyabalẹ awọn ilu kekeke ti ibẹru wa fun u, eto ẹnu ala ipinlẹ kọkan ati ọpọ awọn nkan miran ti o jẹ pataki - pataki ti o yẹ ki o ni iyanju ki ominira ti ao gba le jẹ ti ayọ ati ifọkanbalẹ fun t'ẹru - t'ọmọ, olowo ati mẹkunnu nilẹ Nigeria, ki enia kan wa jẹ kumọyo tan ko sọ wipe ki a pa eyini ti sapakan di ẹhin ti a ba gba ominira, njẹ ominira alafia ni a nfẹ gba tabi ti fiafia ?

Afi wosika wa yi ke si awọn Olotu ijọba ipinlẹ Nigeria mẹtẹta yoku, Olotu ijọba Apapọṣẹ, ti Iwọ - Ọrun (Arọmadahun ọkunrin) ti Ariwa, l'Oke - Ọya (Gambari ọmọ kawo nganni) ki nwọn ba wa fi eto yanju gbogbo idiwọ ti o somọ ominira ki aiya ilu le balẹ ati awa enia inu rẹ ki ominira alafia to wa gori rẹ.

Ọrọ isọkusọ ni awa ka imọran Dokita Azikiwe yi si, nitoripe "Enia kole fi ina s'ori orule ki o sun sinu ile".


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.



# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

## Rest House, Club Road, Ikoyi.

The Electricity Corporation of Nigeria invites tenders from contractors in Category D and above of the Federal Ministry of Works List of Contractors for the construction of a Rest House at Club Road, Ikoyi.

The Form of Tender, Conditions of Contract and Bills of Quantities will be forwarded to contractors who fall within the categories stated above and whose applications together with a deposit of £5, are received by:-

The Secretary,
Electricity Corporation of Nigeria,
Electricity Headquarters,
Private Mail Bag 1001,
Ebute Metta, Lagos,

not later than Tuesday 7th October, 1958.

Upon receipt of a bona fide tender the deposit of £5 will be refunded.

It is essential that the contractor shall be in a position to provide evidence of financial stability and of having successfully carried out contracts of a similar nature.

The Electricity Corporation does not undertake to accept the Lowest or any tender.

Further information concerning the contract may be obtained on application to the Civil Engineer at this Headquarters.

**Arthur Faul**
SECRETARY TO THE CORPORATION

Eletricity Corporation of Nigeria,
Eletricity Headquarters,
Ijora.
Private Mail Bag 1001,
Ebute Metta.


## Ogbeni Akinola Di Ijoye Egba

ABẸOKUTA. Ọgbẹni E. Akinola Cole ti o nṣe Adele Adajọ agba ti o mbẹ ni kotu Ake. Grade "A" Customary Court nigboro ilu Abẹokuta ni Kabiyesi Sir Ladapo Ademola Oba Alake Abẹokuta fi oye nla ti awọn Ologboni ti a npe ni ADILA, da lọla. Lọjọ Saturday 27th oṣu Sept. 1958, ni nwọn yio ṣe ti awuye-wuye iwuye na, ti nwọn o si ja ewe oye le Oloye titun na lori.

A wa Oniwe Irohin Eleti-Ọfẹ fi eyi ba Adajọ na yọ gidigidi fun ilọsiwaju, Ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ, ẹ ko ni ṣe e ti o.


## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.

# Oga Ise To Fa Aso Olopa Ya, San Ogun Poun

IJẸBU - ODE. Ọkunrin kan ti o nṣe ọga agba nibi iṣẹ ni awọn ọlọpa ramu, ti nwọn fi sun ẹsun wipe, o fa aṣọ ọlọpa ya tan, o si wa mọto rẹ ni ọna ti o fi le wu enia lewu.

Bi a ti gbọ ti ọrọ na si niyi. A gbọ pe, ọga ibiṣẹ kan gun kẹkẹ (Motor-Cycle) ti ọwọ rẹ si nju si ọtun ati osi, ni ọlọpa ba da duro, nwọn ni ki o mu iwe aṣẹ rẹ wa, o si kọ lati muwa, ni on pẹlu ọlọpa ba di mọ ara won, ni ẹwu ọlọpa ba ya.

Ọga na dahun pe, nigbati o mbere iwe aṣẹ ti on fi nwa mọto wipe ki on muwa, on ko mọ pe ọlọpa lo mba on sọrọ. Owe Yoruba kan sọ wipe, nigbati iwọ ko mọ pe aja ni, ti o si na a ni kumọ, njẹ iwọ ko ni mọ pe aja ni, nigbati o gbọ igbe rẹ. Adajọ ṣa konko ogun poun mọ lara tabi ẹwọn oṣu meji

# Obinrin Kan Bimo Ibeji ninu Ile Idibo

BENDE Obinrin aboyun kan, ti o lọ dibo lati yan aṣoju sinu igbimọ ibilẹ ti ilu wọn Ala-Ala, nilẹ Bende ni a gbọ wipe o bimọ ibeji si ibiti o gbe ndibo ninu ile idibo.

Ọkọ Obinrin na sọ fun Oniwe irohin kan wipe orukọ ẹniti o ba ṣ'orire wọle ni on yio sọ ọkan ninu awọn ọmọ meji na, on yio si sọ ekeji ni orukọ akọwe igbimọ ibilẹ na.

"Rapid" NUT CRACKING MACHINE
Ẹrọ t'o nyara pa ekuro ati iru eso lile bẹ ẹ.
Ẹo ri ra ni
LEVENTIS MOTORS LIMITED
(Technical Dept)
Ebute-meta, Ibadan Kano, Aba ati Port Harcourt.

Kere o !

Ati ni oriṣiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ kio to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road Lagos

# Oba Onitsha Mbo Wa Sile Laipe

Oba ilu Onitsha ti o ti ilu re de silu Eko laipe yi, ti o si woko Oyinbo ba won lo silu Oyinbo fun eto Ominira ile wa ni a gbo pe yio pada de si Onitsha ni Saturday ojo 4th osu October 1958. Ohun ti o fa sababi ti dide re fi ya kiakia be, a ko mo.

A gbo wipe awon omo ilu Onitsha yio lo pade re ni Ikeja tabi ni Apapa.

Gba ilera, agbara ati imaraya





Bi mo ti da laipẹ yi re. Iyonu ehin didun, orẹ ati iwora ko si igbadun fun mi tabi ere.


Bẹẹ ọrẹ mi sọ pe "ohun ti ara rẹ nfẹ ni awọn koro De Witt's nwọn a le oro irora jade lara rẹ nwọn yio si mu ọ lara da.



Mo ti oju mi ri bi De Witt ti nyara ṣiṣẹ lara lori awon eree inu mi si ati bi awọ itọ mi ti ṣe yipada.


Nisisiyi - ko si ehin - didun mọ ara mi da ara mi ti le to lati ohunkohun. Mo dupẹ lọwọ De Witt's Pills.

Iwọn-iba TITUN ti a le fi dan an wo

O le ra De Witt's Pills oni iwọn - iba fifi dan an wo titun yi, ki o si dan an wo funra ara rẹ. Nwọn a le oro buruku jade kuro ninu ara re a si duro bẹ e

LAKUREGBE, ẸHIN-DIDUN, LATANLATAN ATI IRORA KAKIRI ORIKERIKE ARA ATI IṢAN ARA

Ra iwọn iba oni fifi dan an wo "De Witt's Kidney & Bladder Pills" titun yi nisisiyi.

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills
yio fun o ni ILERA, AGBARA, ati IMARAYA

# Ariwo Ge e Lehin - ola Asuke To Bi Gbajumo.

Nigba lailai, nilẹ Oke, Ọkunrin kan wa ti o jẹ Asuke o jẹ ẹniti o bi awọn ọmọ pupọ. o bi ọkunrin o si bi obinrin pẹlu. gbogbo awọn ọmọ baba Asuke yi lojẹ gbajumọ Councillor, Minister, Sẹkitẹri ati Senior Service ati Iyalode.

Li ọjọ kan baba Asuke yi pe awọn ọmọ rẹ jọ, o wi fun wọn pe. "Ẹnyin ọmọ mi, ariwo ge-e lẹhin - ọla. Asuke to bi gbajumọ' O si dakẹ.

Awon ọmọ baba Asuke yi bere lọwọ baba wọn pe, kini lajori ọrọ ti o sọ silẹ yi, baba wọn Asuke dahun pe on ko ni sọ ju bẹ lọ. Nigba gbogbo ti awọn ọmọ baba yi ba nṣe apejọ ni baba Asuke yi ma nsọ wipe "Ariwo ge-e lẹhin-ọla Asuke to bi gbajumọ. Awọn ọmọ baba yi fi ọrọ ti baba won so yi wẹlọ lọdọ awọn agbagba, sugbọn ko ri ẹniti o le fun wọn ni itumọ ọrọ na, awọn ọmọ baba na ka si wipe' nṣe ni baba wọn nṣe aran. Sibẹ baba yi ko dẹkun lati ma sọ fun wọn pe ariwo ge e lẹhin ọla, Asuke to bi gbajumọ.

Nigbati o ṣe lẹhin ọpọlọpọ ọdun, ni baba Asuke yi ṣalaisi. Ọba ranṣẹ de wipe on Ọba lo ni oku na ẹnikan ko gbọdọ fi ọwọ kan oku na rara.

Lẹlẹ tẹlẹ nilẹ Yoruba, ofin wa wipe, bi asuke kan ba ku ninu ikoko Odu. Koko (Aro) ni nwọn ni lati gbe si ki nwọn to sin oku rẹ, ọba ilu lo si ni lati ṣe gbogbo inawo na.

Nitorina nigbati ọba gbe koko de tilu-tifọn lati fi sin oku baba asuke na, kinla ! ni awọn ọmọ Asuke ti o jẹ gbajumọ ba tutọ soke, ti nwọn si fi oju gbaa nwọn wipe rara o! ni iru ipo ti awọn wa yi, ki ẹnikan wa fi koko sin oku baba wọn, irọ ni, awọn ko ni gba, Akika ni awọn, awọn ti to ara wọn ni kika, awọn ko bẹ ọba ki o wa ba wọn sinku baba wọn nwọn ko si ni kọhunkohun ti o le ti idi rẹ bọ.

Eyi ti a nwi yi pẹ gbogbo ilu ti nrọ gidigidi, awọn ọmọ lẹhin ọba ti ngbaradi fun ijagboro, awọn ọmọ oloku ti o jẹ gbajumọ ati ijimi enia, ti lọ fi owo ko awọn Sabarumọ jọ fun ija na.

Nigbatio ṣe nibaba alagba kan sunmọ awọn ọmọ oloku o wipe "Ariwo ge e lẹhin-ọla, Asuke to bi gbajumọ" Awọn ọmọ oloku tagiri, o wi fun wọn pe ohun ti baba nyin bṣọ tẹlẹ fun nyin lo dẹlẹ yi, nitorina na ki nwọn jawọ kuro ninu apọn ti ko yọ, ni nwọn ba yago fun ọba, nwọn si fi koko sinku baba wọn.

---

# Suru Ni Baba Iwa

Lati ọwọ ẸṢỌ

Ọkunrin Alufa kan wa, ti o kewu-kewe, o hantu, o fa tẹsuba fa, tẹsuba sibẹ agbara kaka lo fi nri onjẹ jẹ. Bi o ba lọ tọrọ owo lọdọ ẹnikan, nwọn o wipe ki Ọlọrun fun u ni suru. Fun nwọn ọdun gbọrọ, ni ọkunrin ba ko ti nr o jẹ jẹ dede

Alufa na wa ro ti r, o fi le ori owe kan ti o sọ pe, "orisa to ba gbeni ni a nsin". Lati ọjọ ti on ti nkirun ti on ngbawẹ, ti on nsin Ọlọrun, on ko ri ohun kan, awọn kefeti ti ko mọ Ọlọrun lo nri owo lo, nwọn ngbeyawo awọn si nsanra batakun. Awọn Alufa ẹgbẹ rẹ nda a lẹkun pe ki o mu suru. Nitoripe nigbati iranlọwọ eda ba pin, nigbana ni ti Ọlọrun bẹrẹ.

Ni ọjọ kan, Ọlọrun ran alejo mẹta si wipe ki o mu ọkan ninu awọn alejo mẹta na. Nigbati awọn alejo na mbọ, nwọn kan odo kan, orukọ awọn alejo na ni, owo Regbọn, ọmọ ni aburo, suru ni abigbẹhin.

Ariyanjiyan de si arin wọn, ọmọ sọ wipe owo ni ẹgbọn ki o kọkọ koja odo na, owo kọ lati kọkọ koja, nigbati ọrọ na fẹ dija, ni suru dahun pe, o to, o gbe owo pọn, o gbe koja, o tun pada wa gbe ọmọ koja.

Awọn alejo na de ọdọ Alufa. Nigbati nwọn ki ẹra wọn tan, nwọn dahun pe ki o mu ẹnikan ninu wọn. Alufa na bere orukọ (1) Owo (2) Ọmọ ati (3) Suru.

Alufa na lọ sọdọ awọn Alufa lati ṣe agbewo nipa awọn alejo mẹta ti o de wa ba yi. Odu ti nwọn ri fun ni nwọn nki bayi wipe.

Owo lẹgbọn, Ọmọ laburo,
Suru ni oogun aiye.
Agba to ni suru

Ohun gbogbo lo ni. Nwọn sọ fun Alufa na pe ki o lọ mu suru nitoripe suru nibaba iwa.

Alufa na pada sile. o mu suru sile o ni ki awọn yoku ma lọ. Owo ati ọmọ pada sẹhin. nwọn nlọ. Nigbati o ṣe nwọn tun kan odo gẹgẹbi ti akọkọ.

Bi owo ti ngbo ọmọ lẹnu awọn mejeji bẹrẹ si bara wọn ja, nwọn ja titi o rẹ wọn, nigbati o ṣe ni owo dide o ni on ko lọ mọ ja bayi titi on yio kuku lọ joko ti suru. Bayi ni Alufa di Olowo ati ọlọla gbẹhin aiye rẹ.

Ẹniti o ba ni suru ohun gbogbo To ni.

---

# Bassey Pari Pep Lori Ekesan



Hogan (King) Bassey, ọmọ ilẹ Nigeria ti ọkunrin ara ilẹ Amerika ti a ti gburo rẹ pe afẹṣẹ kan yọ ẹhin meji ni iṣe ni a gbọ pe o pe Bassey nija, ti nwọn si ta porogan ija na ni ọjọ Saturday to-koja ni Bassey lu ni alu yọkẹ lori ẹkẹsan. Owo ti Basey gba lori ija na je ẹgbẹji poun.

A gbo wipe awọn miran tun ti npe nija lọwọlọwọ yi......

---

Bi Iwo Ba Fe Je'Gbadun Ra Siga BICYCLE Ti O L'okiki Nile Nigeria



# Olotu Ijoba Iwe-Orun Ile Nigeria



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Obafemi Awolowo, nigbati o gunle silu oyinbo, awon omo ile Yoruba lo pade re.

Ninu awon enia ti o lo pade Oloye Awolowo ni okunrin ajeji, ara ile Amerika kan ti nwon npe ni Paul Robeson, alawo dudu, ti okiki re kan gidigidi ninu orin kiko akorin olohun'yo ni. Inu Oloye Awolowo dun lati ba okunrin na pade, nitoripe o ti ngburo re lojo to pe.

## Egbe Erinmo Morning Star Ibadan Branch Se Ipade

(Obere loju ewe keji)

o'u to oro na.

S.M. Ojo ni ojo kan on pe Ibadan ni nwon ti nmse si on lati ile pe awon ko eru lo ni ile. S. Obisakin ni o ye ki a fi oro na han Ijoba. Ezekiel Olowoyo si ni on kejl oro re. S.T. Ogundele ni oro ole na di igbagbogbo ni Erinmo. O ni ko si ole kan ti nja ni ilu ti awon omo ilu ko mo. S. Olu Ojo ni oro ole ilu Erinmo to amojuto. Micheal Yeye si soro nipa awon Egbe yi ti o wa kakiri o ni eniti ko bafe feti si oro ilu re o ni bawo ni ki a ti se ?

Paul Ekemode so pe ko si eniti ngbo oro ilu re ti ko ni feti si. Ezekiel ni o ye ki a gbe enia dide lati lo si ilu ibiti nwon ko ti fe gbo oro ipade yi. Gabriel Ojo ni a nse ipade ni agbegbe bi Akufo t a-b-i Akinyele ati Latepon. O ni ira eniti ko ba fe lowo ninu ipade yi o ye ki nwon nu si iwaju ijoko ni ipade miran ti a ba se Ijoko si ran ran enia meji lo Agbati ; nwon si ran enia meta lo si Ile, lati lo se eto rike. Awon ijoko ipade yi si fi ipade miran si osu meta. Ipade yi si pari ni agogo meji koja ogbon iseju

Olotu

Mo dupe pu o lowo nyin fun aye ti e gbami ninu iwe irohin yin Oloyinmomo. Owo n'm yio ma roke. S.T. Ogundele.

"CAMBRIAN" ERO AFOWOYI T'ONRIN GBAGUDA

O nrin gbaguda mulomu o o si ni alope ni ile Nigeria

Eo ri ra ni £27. 10s lodo.

LEVENTIS MOTORS LTD
(Technical Dept)
Ebute Metta, Ibadan, Kano, Port Harcourt ati Aba.

## Olotu Ijoba Apapose Nilu Oyinbo



Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, ti o nse Prime Minister apapo Ijoba ile Nigeria da a[illegible] awon onirohin ilu Oyinbo lohun nipa ibere won, o wipe, Ogbeni Nassar, alase ile Egypt nfi mo-daku sere ni [illegible]

Alhaji na so wipe, enikeni ti o ba nf[illegible] si orile Afrika tabi wahala, ota lo ye ki a [illegible] si. O so wipe, ni akoko y i ti a ngber[illegible] ile Nigeria ni Ominira ati ilosiwaju n i[illegible] nwon nfe da ijogbon sile eyi ti o le di ilosiwa[illegible] ile wa lowo.



# LAGOS RACE CLUB

## October Meeting

## Saturdays 4th, 11th, 18th, 25th October and 1st November, 1958.

### FIRST DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE No. 2 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE No. 4 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE No. 5 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 6 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No. 7 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 5.45 p.m. |
| RACE No. 8 | Five Furlongs Handicap Top "A" Division | 6.15 p.m. |

### SECOND DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 2 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.30 p.m. |
| RACE No. 3 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4.00 p.m. |
| RACE No. 4 | Ten Fuslongs Handicap Middle Division | 4.30 p.m. |
| RACE No. 5 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5.00 p.m. |
| RACE No. 6 | Five Furlongs Handicap Top Division | 5.30 p.m. |
| RACE No. 7 | Eight Furlongs Handicap Top 'A' Division | 6.00 p.m. |

### THIRD DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE No. 2 | Nine Eurlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE No. 4 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE No. 5 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 6 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No. 7 | Seven Furlongs Handicap Top Division | 5.45 p.m. |
| RACE No. 8 | Ten Furlongs Handicap Top 'A' Division | 6.15 p.m. |

### FOUTH DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE No. 2 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE No. 4 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE No. 5 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 6 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No. 7 | Polo Scurry 4 Furlongs | 5.45 p.m. |
| RACE No. 8 | Nine Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |

### FIFTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE No. 2 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE No. 3 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 3. 45 p.m. |
| RACE No. 4 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 15 p.m. |
| RACE No. 5 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No 6 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No 7 | VICE CHAIRMAN'S PRIZE Ten Furlongs Handicap Top Division | 5. 45 p.m. |
| RACE No. 8 | Six Furlongs Handicap Top "A" Division | 6. 15 p.m |

P. o. 122

## PRESS RELEASE

EXCHANGE CONTROL (IMPORT & EXPORT) (Amendment) Order 1958

With effect from the 1st of May, 1958 the Exchange Control (Import and Export) (Amendment) Order, came into operation. By this Order the Minister of Finance has removed the prohibition on the importation of currency notes of any kind, and the importation of securities other than bearer securities.

The existing provisions relating to currency notes which may be exported from Nigeria by a traveller still remain, although this is now £10 in respect of U.K. or West African Notes and £100 in other notes.

(Sgd) A. KARIMU
Exchange Control Officer

## Ole Aji Keke Wopo Ni Agbegbe Ila - Orun

UYO. Ni agbegbe Ila - Orun, kẹkẹ (Bicycle) ni jiji ko nṣe ohun ajeji, bi kẹkẹ basikulu ba si sọnu, o ṣoro gidigidi ki oluwarẹ to le ri gba pada. Kẹkẹ basikulu ni jiji ko jamọ ohun kan mọ. Bi ẹnikan ba lọ fi ẹjọ sun wipe nwọn ji kẹkẹ on lọ, nwọn o sọ fun pe ko mu suru. Pẹlupẹlu awọn ti o ji kẹkẹ na, ko ni gbe duro nitosi ibiti ọwọ ọlọpa yio tẹ wọn. Eyi nikan tilẹ kọ, ọpọlọpọ ni ohun ti nwọn o yipada lara rẹ, nwọn o si tun kun lọda, tobẹ bi ẹniti o ni ba ri i, ko ni mọ ọ.

Ni abule kan ni eti ilu Uyo ni ọlọpa gbogun lọ ja abule na, kẹkẹ basikulu ti nwọn ri gba ti nwọn kori iwe ti nwọn fi ra a to iwọn ọgọrun. Nitori ọlọpa ṣọwọn ni apa ibẹ.

Awọn enia ti nwọn taku lati gbe kẹkẹ wọn ju silẹ ti nwọn si lọ fa ibọn yọ si ọlọpa to iwọn egun enia. Irohin ti kan lọ ba awọn ẹgbẹ wọn yoku, nipa ohun ti ọlọpa ṣe yi, ọpọ enia ti gbe kẹkẹ wọn sa wọ igbo lọ.

Nilu Abakaliki bakanna ni awọn ọlọpa nyẹ awọn kẹkẹ wo, ogunlọgọ ni awọn kẹkẹ nwọnyi ti nwọn ji gbe, ṣugbọn a koiti ri ẹnikan lati wa yẹ wọn wo.

Printed & Published by The ... Printing and Publishing Company, 2x ... Street P.O. Box 467 Lagos Phone 2117